# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 66. SATURDAY, OCT. 13, 1923. Fourpence.



**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware. Beer. Wine. Iron Bedsteads. Ruley Plates. Rubber Beads of all kinds. Clay and Briar Pipes. Champagne. Cement. Biscuits in cases. Gun Powder. Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice. Accordeons. Piano. Padlocks. Beads etc., etc., etc."**

---

Ọgbẹni DURO THOMAS

Onișowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to șẹșẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.


16 OCT. 1923







Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati 'șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panutkikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun xikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

---

## The British Psychological Institute

OF BOLTON, ENGLAND,

teaches by Correspondence the following Sciences :—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc.

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

---

## WANTED.

2 smart but reliable boys for Newspaper Work. Good pay to deserving ones.

*Apply to the Editor.*

---

## THE LAGOS HOTEL

Iced Drinks of every description on sale at the above popular Hotel.

Clients' comfort occupies a prominent part in the programme of the establishment.

Billiards playing forming a centre of attraction.

**TERMS :—Strictly Cash.**

H. H. KING,
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

## ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu olomi didi to np'ongbẹ enia nbẹ nihin lorişirişi fun tita.

Ko si ọna ti a ko ngba fi tẹ awọn onibara wa lọrun.

*Billiards* idaraya si wa fun ẹnikẹni lati fi ṣere. Owo-lọwọ la fẹ.

H. H. KING,
*Oni-nkan.*

Ita Ọja Ajaṣẹ, Eko.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

### B' ARAIYE TỌWỌ B' APO B' O FUN Ọ L' OBI, MA JẸ!

Orin yi ni ẹnikan to nję Belo ko ranti lati kọ ni ọjọ diẹ sẹhin nigbati o fi gba obi jẹ lọwọ ẹnikan to nję Gadamọsi l' Oke Arin; a gbọ pe nigbati ọkọnrin ele'ekete yi fẹ fi jamba na şe Belo, aya rẹ (eyini ni aya Gbadamọsi papa) ni Gbadamọsi ran si i pe ki o wa fi oju kan on ni Oke Arin; nigbati Belo si de ibẹ, ko ba Gbadamọsi nile; aya Gbadamọsi si rọ pe on papa ni on npe Belo pe ki o ya on ni şile marun; Belo wo fẹ o ni "ohun ti o gbe mi jade lati ile wa sibi leyi, kinişe ti o ko sọ bẹ nigbati o de ọdọ mi? O, oşe o, nko ni şile marun to wi" nibiti nwọn gbe funtọ si ara wọn loju bayi, bẹni Gbadamasi de ko şe bi ẹnipe on gbọ ohun ti nwọn nsọ titi Belo fi fi ẹlọ aya rẹ san u,; Gbadamọsi ni ko mu ẹnu kuro pe ọrọ obinrin ko to tẹle; Gbadamọsi ati Belo si mu ọrọ miran sọ; nibiti Gbadamọsi ngbe sin Belo ọrẹ na lẹhin igbati nwọn ti pari ọrọ-sisọ tan bẹni Gbadamọsi tọwọ b' apo o ni Belo, obi re bẹni onitọhun si gba o si da şẹnu peu; o si fun Alli ọrẹ rẹ miran jẹ; bi Belo ati Alli kuku ti de 'le, bẹni oro mu tọtun tosi wọn nibiti nwọn gbe nbi Belo lere pe bi o gba nkan jẹ ni, o jẹwọ obi ti Gbadamọsi fun on, nwọn si tun lọ sile Alli gbirigbiri ni Alli papa nvira nilẹ fun oro ogun ti Gbadamọsi ti fi s' obi yi; iyoku iregbe, nwọn lọ ra Gbadamọsi mu; ọran di ti Kotu awọn ọlọpa; ko si ẹri gbamọşin kan ti a o fi ko Gbadamọsi ọdaran yi loju ọpẹlọpẹ Dr. Sapara ti o la ọna ti awọn ika enia miran fi nfi iwọ si obi fun awọn ẹlomiran jẹ Dr. Şapara sọ pe abẹrẹ titun ni irufẹ awọn alakọri ẹnibẹ nlo fi ogun na si obi nipa fi fi abẹrẹ na gun ara obi kakiri pẹlu ogun yi lẹhinna nwọn a tete fun ẹniti nwọn ba fẹ şe loşẹ jẹ bi bẹko, obi na yio di dudu ni iwọn ijọ meji tabi mẹta ti nwọn ko ba tete ri oluwarẹ. Gbadamọsi ni otọ ni Dr. wi o ni şugbọn ẹja ni on fi t' on pa—A ko mọ bi ẹja ori atẹ ni Belo jẹ fun u—ẹri Dr. Şapara tẹ Adajọ lọrun tobẹ ti a fi sọ pe Adajọ na dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Dr. Şapara fun alaye ọrọ yi; o si ju Gbadamọsi sẹwọn oşupa mejila ni *Monday* ọsẹ yi pẹlu işẹ aşegan. A gbọ pe a fun awọn mejeji yi ni egboji apa ogun fun si san wọn. Bẹ gẹgẹ ni Gbadamọsi yi ti şe fun ẹnikan ti o nję Braimah ni Ileya to kọja şugbọn onitọhun ko jẹ ki edi mu on nitori ko jẹ obi na lojukanna; nşe lo ju si Ajúfú (Apo) ẹwu rẹ şugbọn a gbọ pe ogun na lagbara tobẹgẹ to fi jẹ ki apakan aiya nibiti ẹwu yi wa şe ribiti.

Ẹnyin ara wa, ẹ raiye tabi ẹ raiye lode, A ko le fẹnu sọ ọgọrọ enia ti a ti fi obi pa nigboro ilẹ yi. Oju l' akan fi nşọri. Agbalagba d'ọwọ nyin o, Ẹnyin kokoro jobijobi!!!

### Ẹ KU EWU ỌJỌ!!

A ba Ọgbẹni E. A. Akintan Oniwe-Irohin Eleti Ọfẹ yọ fun ewu to rekọja lori rẹ ni *Monday* ọsẹ yi. Ni *Saturday* to kọja ni Oyinbo F. B. Mulford Aşoju awọn Ẹgbẹ Onisowo Oyinbo Agbẹ'a, *Lagos Stores Ltd.*, Ẹhingbẹti fi Ofin Amunimuye (*Criminal Code*) mu u pe o sọrọ Alufanşa si on lara ni oşu to kọja ninu Iwe Irohin rẹ kan, Adajọ si gba ẹbi ti Ọgbẹni Oniwe-Irohin yi ni on jẹ nitorina "ko pẹ ni ikunlẹ." Ọgbẹni *Lawyer* E. J. Alex Taylor ti o jẹ agbẹjọro oyinbo yi si gba ẹbi ati ẹbẹ ti

Ọgbẹni *Lawyer* Ọlayinika Alakija bẹ ni Kotu niteri Ọgbẹni Akintan na.

Adajọ fi oke le pe ki Ọgbẹni Akintan san owo irin ẹsẹ ẹjọ yi ki o si tẹ Iwe Itumba fun Ọgbẹni Mulford si Iwe rẹ ati si gbogbo Iwe-Irohin toku nilu.

ẸGBẸ EKITI PARAPỌ MA ṢE BẸBẸ.

A ṣe Ipade gbogbo gbõ ti awọn Ẹgbẹ yi ni Ile Afari Ogun ni *Tuesday* ọsẹ yi; Ohun pataki ti a sọ ni ti ẹyẹ ti Ẹgbẹ yi fẹ ṣe fun Dr. Oguntọla Ṣapara I. S. O. baba Ẹgbẹ na fun Ọla ti Ọba King da a ni oṣu diẹ sẹhin. Ninu ariya na a sọpe awọn ọmọ Ẹgbẹ na yio jo ijo ilẹ wa ni Ita Balogun nwọn yio si wa fi abọ si Ile Afari Ogun fun ere ṣiṣe pẹlu; a wi pe ki gbogbo Ẹgbẹ da iba owo ti ipa wọn ba ka fun ẹyẹ na; a koi ti fi ọjọ kan pataki si ọrọ ariya na titi owo a fi jọ.

Diẹ ninu awọn to sọrọ ni:—

Dr. O. Ṣapara I.S.O., Ọgbẹni D. Ṣaṣẹgbọn Lawyer, J. Stanley Benjamin Ọgbẹni C. J. Haastrup Dr. Ayọdeji Oyejọla ẹniti o fi irukẹrẹ ti Alake fi da Dr. Ṣapara lọla han gbogbo Ipade, Ọgbẹni Braithwaite, *Editor Eko Akete*, Ọgbẹni Atẹrẹ ati awọn jakanjakan miran.

Ẹ ṢEUN, DE GAYE ATI BEECROFT.

A dupẹ Iwe "Yoruba Composition" ti awọn Ọgbẹni yi fi ṣọwọ si wa ninu ọsẹ yi; papin ni Iwe na fun awọn to ba nfẹ mọ ede Yoruba ati Gẹsi siwaju. A nta ni "Ṣabu" C. M. S. nibi, Ṣile meji abọ pere ni Ọkọkan; ẹkọ inu iwe na ju ti oni pọun kan lọ.

ỌGBẸNI R. B. REIS, SAKA RẸ NI YI. GBERE RẸ.

Inu wa dun nigbati a gbọ pe Adajọ Agba ri si ẹjọ ti awọn ọlọpa mu wa siwaju rẹ ni ọna *Appeal* nipati iwakiwa awọn ara Calabar ati Kunakuna eyiti a sọpe Adajọ kekere ni on ko ri si nijelo nipa ti iṣe pansagati awọn obinrin wọnyi nṣe lojukọja nibi ninu eyiti nwọn jẹ Aṣajẹma-sẹ; ẹnyin ọkawe wa yio ṣakiyesi pe Ọgbẹni R. B. Reis Ọga atata ti o si jẹ Olori awọn Ọlọpa inu ilẹ yi lo ṣe ọdẹ ti ọwọ fi tẹ

Ogunlọgọ awọn onigba-egbere wọnyi nigbati a ra nwọn mu nibi ni oṣu diẹ tokọja.

A DUPẸ ỌJỌ.

Awọn Ọgbẹni Jinadu ati David Belo Ọṣuntolu dupẹ gidigidi lọwọ awọn Ẹgbẹ ati Ọgba to wa ba wọn daro nigbati Iya wọn Jarinatun Ọṣuntolu tẹrigbaṣọ ni lọlọ.

O DABỌ O.

*Archdeacon* ti Eko lọ si Badagry lana fun isin kọre awọn Ijọ C. M. S. to wa nibẹ, ọkọ a re fo o.!!

BALẸ ỌKỌ ILU, Ẹ KU OHUN OJỌ.

Ọgbẹni Henry Carr. M.A., B.C.L., I.S.O. Balẹ ilu sọ Asọye kan nipa "Isin ati Igbesi aiye wa" ni "Ṣùkurù" Faji lalẹ *Tuesday* ọsẹ to lọ; fun Ẹgbẹ Ọmọde-mọsẹ onigbagbọ *Church* Alagogo. Ẹsẹ pe ṣọṣọ nibi ọrọ Ọgbẹni yi.

Bẹbẹ ni ki a ma ri o.

---

OYINBO F. MULFORD
ATI
"ELETI ỌFẸ."

Si Oniwe-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Li owurọ Satide ọsẹ ti o kọja, October 6, ni Ijọba ra Oniwe-irohin "ELETI ỌFẸ" mu ni mọwọ-mọrun; ẹsun ti a fi sun u ni pe o ta korangbọn si apakan Ofin (*Criminal Code*) nipa sisọ a-sọ-ma-sọ si OYINBO F. MULFORD lara nipa ẹ ãjo ti Oniwe-irohin na sọ wipe Ọgbẹni Oyinbo na ṣe, ki awọn enia le yan a si Igbimọ Aṣe'lu lati ṣe oju wa nibẹ.

Ninu gbogbo awọn mẹwẹwa ti a di 'bo fun, ẹniti o ba wipe on ko ṣe ãjo rara lati wọ ile, irọ ni oluwarẹ npa. Ani Lọya Wilson ti o tilẹ jẹ wipe enia meje pere li o di 'bo fun u, ṣe ajo ati wọ ile, nigbati o san pọnwun mẹwa fun Ijọba pe ki a le ka on kun awọn ẹniti a o di 'bo fun. Candido Da Rocha si lẹ ogunlọgọ iwe mọ ara ogiri Eko ati Ebute Mẹta, ti o fi nkẹ si Ilu pe ki nwọn d'ibo fun on, bẹ gẹgẹ si ni Lọya Alakija kekere ati

jakan-jakan miran ṣe ajo pẹlu. Malu ti o nṣe awure lati li ọla bi Erin, ati Ọpọlọ ti o nfẹ fò lati tobi to Malu, ajo ni awọn mejeji jumọ nṣe; ṣugbọn bi ajo wọn ba si da jo wọn li oju, eyini ko kan ẹnikan.

Orișirișí àjo li o wa; ajo li obi, ajo li akọ. A ko si ro pe ẹnikẹni ninu awọn mẹwẹwa ti a di 'bo fun ṣe akọ ajo ti o lodi si ofin Ijọba, tabi ajo ti o le gbe wọn de Ọgba-oni 'go.

FREDERICK BARON MULFORD jẹ *Agent* tabi Oyinbo Akọwe-agba fun Lagos Stores. O ti de ilẹ yi pẹ diẹ, enia atata ni, o si fẹran enia dudu, papa awọn onibara rẹ; pupọ ninu awọn ọdọmọkọnrin wa ni a si gbọ pe o nba ṣe ọrẹ. Li aisi ani-ani, irẹpọ yi ati ifẹ ti o ro pe on ni fun ire ilu yi, li o jẹ ki o ke si wa pe ki a wa di 'bo fun on. O wa gbagbe wipe bi ọrẹ timọ-timọ ba kú, iyekan kata-kata li o ma gbe e sin. Jubẹ lọ, Ọgbẹni Oyinbo MULFORD kọ li o ni Ṣabu Lagos Stores, Aṣ'oju wọn lasan li o jẹ nibẹ. Ko si si ohunkohun ti o le ni ki awọn Ọga rẹ ma gbe kuro ni ilẹ yi nigbakugba ti o ba wu wọn lati ṣe bẹ, ki nwọn si fi ranṣẹ si Jẹriko tabi Jerusalẹmu, iyẹn ti ọwo wọn ba wa nibẹ.

Oyinbo F. MULFORD jẹ ọkan ninu awọn meje ti ẹṣin wọn ṣ'ẹṣẹ ninu ire-ije ati lọ si Igbimọ Aṣẹ'lu. Oniwe-irohin "ELETI ỌFẸ" rohin eyi si inu Iwe rẹ ti September 26, nwọn si ra a mu ni ọjọ Satide ọsẹ ti o kọja fun ohun ti o sọ nipasẹ Oyinbo na. A ba a ro ẹjọ ni Kôtu Onidajọ kekere ni Monday ọsẹ yi, nigbati nwọn si bi i lere ẹjọ; o ni—To-to-fun, Mo jẹbi! o tọrọ idariji, o si ṣe ileri wipe on yio fi ẹnu gbo ilẹ fun MULFORD ninu gbogbo Iwe-irohin ti o mbẹ ni ilẹ yi.

Ki Ọlọpa to mu E. A. AKITAN, Oniwe-irohin yi, ni ojora ti mu u bi obirin ti o nrọ 'bi; a ko si gbọ wipe o ti nyan ẹlẹbẹ kiri lati ọjọ Friday, ki nwọn to mu u ni ọjọ Satide. Nigbati nwọn jaja duro fun u, o fẹrẹ le bura wipe, lailai, on ko ni ṣe Iwe-irohin mọ.

Anu rẹ ṣe wa gidigidi, o si ṣe ọpọlọpọ enia pẹlu ti nwọn fẹ ṣe iranlọwọ fun u; ṣugbọn ko fun wọn li aye rara—nṣe ni o ngbọn kiri jinni-jinni, ojo rẹ si ju ti akata lọ. A mọ wipe ko si ẹniti ọwọ Ijọba ma tẹ, ti ko ni damu; ṣugbọn ko dara ki enia ṣe ojo a-ṣe-ju, ki o si sa i-sa-ku-sa, iru eyiti Oniwe-irohin "ELETI ỌFẸ" sa, ti a si gbọ wipe o ndọbalẹ kiri bi Ejo, li ọdọ awọn ti o yan ni ẹlẹbẹ; Ṣiọ!

Eyiti "ELETI ỌFẸ" sọ nipasẹ Oyinbo MULFORD ko kan wa, a ko ran a ni iṣẹ, a ko si gbe e li ẹsẹ rara. Ṣugbọn bi ko ba nṣe otitọ ni Oyinbo F. MULFORD lọ si Apejọ tabi Ipade awọn *People's Union* ni Ilupesi, ni ọjọ Wednesday, September 19; ti ko ba si nṣe otitọ li o ṣe ileri nibẹ wipe on yio ko Motor-Cars mẹdogun jade ni ọjọ idi 'bo fun awọn Ọmọ-ẹgbẹ *People's Union* lati wọ wa fi di 'bo fun on MULFORD, ALAKIJA ati ỌBASA, gẹgẹ bi ati gbọ: bi ko ba si nṣe otitọ ni o ko Motor-Cars jade li ọjọ idi 'bo, ki o jọwọ, ki o jẹ ki emi Atari-Ajanaku mọ, lati sọ ọ fun Ilu bẹ gẹgẹ.

"EKO AKETE," ki ẹ gbo, ki ẹ tọ; ikọ ki nkọ Ejo li ẹsẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,

ATARI-AJANAKU.

[Itara ti Ọkọwe wa yi ni si Oniwe-irohin "ELETI ỌFẸ" nipa ọran rẹ, li o mu u ki o fi kọ iwe bi o ti kọ ọ yi; ki ṣe wipe Ọgbẹni na nyọ ọ ni.

Ẹ sa mọ wipe—Bi ara ile-ẹni ba fi ori gba, ija li o nda.—*Editor*, EKO AKETE.]

---

NIGERIA CIVIL SERVICE UNION

Lagos, Nigeria,

5th, October, 1923.

OFFICERS & COMMITTEE MEMBERS FOR 1923-1924.

Dear Editor,

I have been requested to write and ask you to be good enough to give publicity in your valuable journal to the changes that have recently taken place in the Officers and Committee Members of the Nigeria Civil Service Union for the year 1923-1924:—

*President*:— Mr. H. S. A. Thomas (Re-elected).

*Vice President*—Mr. A. E. Carrena, do.
do. do. „ C. B. Olumuyiwa, do.
do. do. „ J. G. O. Baka Torto,
do. do. „ G. N. Martins.

*Honorary Secretary*—Mr. S. J. Marsh,

*Assistant Secretaries*:—Messrs E. O. Wey, Edmund A. Allen and Magnus A. Williams

*Honorary Treasurer*:—Mr. D. T. Sasegbon, (Re-elected)

*Financial Secretary*:—Mr. A. G. R. Nylander, (Re-elected)

*Auditor*:—Mr. H. W. Thomas.

*Committee Members*:—Senior Representatives of the various Departments and Messrs. W. B. Lemon, Magnus A. Williams, J. B. Liverpool, E. O. Wey, D. R. Bowlay-Williams and S. Q. Sagoe.

2. Thanking you in anticipation,

Yours respectfully,

S. JAMES MARSH,

*Honorary Secretary*

The Editor, "Eko Akete"
Lagos.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, October 13, 1923.

### AWA ENIA DUDU HA RẸHIN NIBI BI OGUNNA? KA MA RI! KA MA RI!!

A gbọ fẹnrẹn ni lọlọyi pe ọkan ninu awọn *Lawyer* wa A-mọ-lẹsẹ bi Iyawo, A-ji sọ didun ọkọnrin, A-pọn-bepo-rẹ, kọwe si Ijọba fun Iṣẹ Agbẹjọro Ọba (*Solicitor-General*): nigbati a gbọ ọrọ yi, inu wa dun gidigidi, a si ṣe l'adura pe ki Baba maṣai jẹ ọhẹn si Iwe nã, nitori a ri pe o to asiko pe ki awọn *Lawyer* tabi *Doctor* wa nilẹ yi wa nipo to "mìjǫ́rìtì" ninu iṣẹ Ọba, iru ki a fi awọn ara wa to jẹ enia dudu si Ipo bayi ko ṣai wọpọ ni Ilu Saro tabi ni Ilu Aganyin; ẹniti o ba nka Iwe-irohin Ilu Aganyin tabi ti Saro, yio ri bi a ti nfi awọn enia wa si Ipo-nla nibi iṣẹ Ọba ati ninu Ilu; Ọgbẹni Woolhouse Bannerman ti o jẹ enia dudu bi awa ni Adajọ Kekere ni Ilu *Cape Coast*; bẹ̃ si ni a sọ pe o to awọn enia dudu bi mẹrin miran ti a tun fi sipo nla bayi ni Ilu *Gold Coast*. Ni Saro, o niye igba ti a fi Ọgbẹni Claud Wright enia dudu ṣe Adele Adajọ Kekere ti a si fi Ọgbẹni Sam Barlatt enia dudu bakanna ṣe Olotu awọn Munisipa ti Saro (*Mayor of Sierra Leone*) kilo ha ṣe ti ko si irufẹ nkan bayi ni Ilu *Nigeria* ti a tilẹ sọ pe o ta gbogbo Ilu mẹtẹta Saro, Ilu Aganyin ati Ganbe yọ ni ọ̀rọ̀ ati dukia? Nigbati a wadi ọrọ yi, a ri pe ki iṣe ẹjọ Ijọba wa nitoripe a tanma pe kosi ninu awọn enia wa bi *Lawyer* tabi *Doctor* ti o kọwe si Ijọba lati bọ si irufẹ ipo nla bayi; boya awọn enia wa nã le rope bi a tilẹ gbà wọn sibẹ, owo ti a o fi lọ̀ wọn ko le to eyi ti nwọn iba mã gbà ti nwọn ba wa gede fun ara wọn: nitoti eyi le ri bẹ̃, ṣugbọn o yẹ ki awọn enia wa mu eyi kuro lọna bi ohun idina, ki nwọn si taputu ati bọ sipo to kà-nkà yi; bi owo ti ao fi lọ̀ wọn nã ko tilẹ to gbọ bukata wọn, ki nwọn "tori iṣu jẹ epo" lati bọ sipo ọla yi ki eyi le fi han awọn enia wa toku nibi ati ni Idalẹ ti nwọn ba gbọ nip[a] ipo nla yi pe Ijọba wa kò ni ikorira ẹnikẹ[ni] lati fun nipo ninu iṣẹ Ọba bi oluwarẹ b[a] jẹ ẹniti o yẹ; bi irufẹ ẹni bẹ ba tilẹ wà [ni] ipo nã fun bi ọdun kan tabi meji, o le k[owe] si Ijọba fun iranlọwọ ati fi kun owo r[ẹ]. awọn mẹta Aṣoju Ilu ninu Igbimọ Ijọ[ba] pãpã ti a ṣẹṣẹ da silẹ yi, ko ni kẹrẹ la[ti] mu ọrọ irufẹ ẹni bẹ̃ wa siwaju Igbimọ fu[n] akiyesi; bi bẹkọ kẹ̀ ti oluwarẹ ba si ri p[e] adanu ni yio jẹ fun on bi on ba wà nipo n[ã] titi, la lai jẹ pe a fi owo ti o jọju kun fu[n] on, o le fi iṣẹ nã silẹ ki o tun mã ba iṣ[ẹ] tirẹ lọ niyatọ bakanna bi ti atẹhin wa, [...] ko pada nibikibi—titi de Kaduna—geg[e] bi ede wa.

Inu wa yio dun ti a ba fi Ipo ti a wi [...] fun ẹni wa nã; nitoripe ogo ipo nã jẹ og[o] gbogbo awa ọmọ Africa.

Nitoripe itakun to-so-gba lo-s'agb[a] lo-so-legede.

---

### JẸNGẸN, ỌBA AGBADARIGI, ỌBA NI L'ỌRUN!

---

Kosi ẹni to ri Jẹngẹn Ọba Agbadarigi ni ọjọ isinmi to kọja niwaju Ijọ Ọmọ Ibilẹ (African Church) pẹlu ilu Oyinbo ati fere bi o ti mura to fa awọn ijọ yi to lọ si Ile Isin wọn ni Ita Uerekete ti ki yio kan sara si wipe "O gbere"

A ṣe ko si ẹniti ko mọ *Ball* jo? Rẹgi ni gbigbe ẹsẹ Ọba pẹlu didun ilu jim, jim, jim, nṣe, tobẹ nigbati nkan na jarunra, Ọba ranṣẹ ni wara ṣẹṣa wipe ki won lọ gbe Agborun nla wa ba on lọna kun eyiti a ti ga le on lori. Wo bi t' Ọkunrin t' Obinrin ti nyilẹ ti Kabiyesi si nkọlu ara wọn; si tun wo bi Ọba papa ti nrẹrin musẹ to nju irukẹrẹ s' ọtun s' osi ni idahun.

Bi Ọba yi si ti jẹ Aborişa sibẹ o fẹran Onigbagbọ, papa Onigbagbọ ti Ijọ Ọmọ Ibilẹ. "Ẹni to ri ọwọ Ikun mọ pe a jẹ oko"

A tọrọ adura nyin fun Jẹngẹn Ọba Agbadarigi, ki Ọlọrun ko le jẹ ko di Opo Jesu mu.

Kabiyesi O! Jẹngẹn! *Amavọn dagbe.*

Ahanfikọ.

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 31.**

To

The Reverend

M. S. Cole, M.A. Inter B.D.

Vicar, Pro. Cathedral,

Christ Church Vicarage,

25, Broad Street, Lagos.

My dear Vicar,

Allow me to congratulate you on the very excellent and outspoken sermon you are said to have delivered in the above place of worship on Sunday last. Really, you are not the sort of man, nor, I am of opinion, is it your trait to cater for the lime-light since your induction into that Church. Those who know you best—and their name is legion and your *modus operandi*—will readily testify to the fact of your always preferring silent yet continuous and ardent working to blowing one's trumpet even at the market-place, with a word of duties with which you are surrounded presently regarding the work of the Church. It is gratifying to learn from your monthly parish Magazine of recent date of another venture at which you are aiming to foster the spirit of Christian cohesion in our midst which unfortunately is lacking amongst us FOR GOOD, at a time such as this, by initiating a series of Services for various Guilds, Professions and business bodies in town, in spite of the fact of your almost being weighted down with the regular work of your Parish.

In all this, it is hoped you will not give way to OVER-WORK, and we would like you, Sir, please to appreciate the underlying meaning of this time-honoured Latin aphorism *Mens sana in corpore sano.*

In fine, that long lease of life, health and strength be vouchsafed you and yours the more from on high, for more usefulness in the Master's Vineyard, is the prayer of your *quondam* pupil,

EKO AKETE.

**No. 32.**

To

Olayimika Alakija Esquire

Barrister-at-law,

15, Bamgbose Street, Lagos.

Worthy Lawyer,

Words fail me to thank you most adequately for your professional services which, I understand, you tendered *free of charge* to the Editor of our Contemporary The *Eleti-Ofe* in his recent trial.

By this magnanimous act, it is not to be supposed that you are in so affluent a state as to need no more retainers for whatever cases in which you may be engaged in future; you volunteered your services GRATIS for the young Editor purely on patriotic and philanthropic ground, and you have shown to all and sundry that Money, though important, counts for nothing with you in the matter of public interest.

Hats off to our popular Barrister.

EKO AKETE.

**No. 33**

To

E. J. Elex Taylor Esquire

Barrister-at-law

8, Victoria Street, Lagos,

Dear Basso Profundo,

May I thank you most sincerely for cheerfully coming to the point of view of your brother-barrister when the latter appealed to the Court to take a lenient view of the recent Criminal Libel, which came before His Worship on Monday last, the result of which being most pleasing to the Defendant-Editor?

Cheerio, good old Alex, you are strict but *kind, sympathetic, and courteous.* All praise to you.

EKO AKETE.

## A LE BINU ORI, KI A FI FILA DE IDI?

A ri iro gbọ wipe awọn kan npe apejọ kakiri, ni ibiti nwọn ti ngbero bawo ni awọn ti le ṣe ri ọna lati fi mu awọn diẹ ninu awọn Ọmọ-ẹgbẹ "Tunluṣe" "*Democratic*" lati fi ẹsun sun wọn fun Ijọba, pe awọn wọnyi lo kọrin buwọn ni oru Saturday, ijọ kejilelogun oṣu September, tobẹ tiwọn lẹ le mafọ ilẹkun mọ awọn lori ni oru ijọ na ki Ijọba bale jẹwọn ni iya ṣugọbn inu wa dun lati gbọ pe, wọn ku nọ patapata ninu gbogbo agbara tiwọn sa—eyi sin jẹ itiju lọpọpọlọ fun wọn to bẹ ti ninu wọn fẹrẹ le salọ fun itiju na.

Ẹnu yami lọpọpọlọ lati ri pe larin iru awọn enia wọnyi, a ri ọpọlọpọ ọmọ-we ninu wọn, a si tun ri awọn ti a le pe ni enia pataki to jẹ pe ko mọ iwe, ṣugbọn bọkini ni wọn jẹ ni ilu a ko sọ ti awọn to npariwo lasan kakiri ilu bi agba ofifo. Mọ pe o tibọ lọwọ wọn, asa ti ngbọ lẹnu awọn alagba bi owe pe "Obọ lọwọ oṣu, oku aran mọju." Eyiti nwọn ba fi sun kaka, ki nwọn ronu jinlẹ, ki ẹmi ba le sọ fun wọn wipe o yẹ, o si tọ; akoko si to fun wọn lati fi ori balẹ fun ilu—ki wọn tọrọ idariji li ọwọ awọn Ẹgbẹ "Tunluṣe" "*Democratic.*"

Ọrọ yi mba onile ati alejo wi—bi ojẹ ara ilẹyi, tabi alejo—ṣugbọn ti ojẹpe on mu osi njẹ onjẹ, ti osin nrin lori ilẹ Eko yi, to sinṣiṣẹ ni bẹ—ẹnikẹni ti Ọlọrun bafun ni agbara lati tun ilu Eko yi ṣe—ko ha tọ ki apawọ pọ ran oluwarẹ lọwọ? Bi wọn ko bi ọ si Eko yi, ajẹ pe orin wa sibẹ—o ṣiṣẹ o ni owo, o kọ ile, o fẹ Iyawo, o si bimọ si ilu yi—njẹ bi eyi ba jẹ otitọ—ara Eko ni iwọ nṣe.

Ko ha han gbangba, ni sisiyin pe Ọlọrun ti fi awọn mẹta bi: Akọni ọkunrin, kiniun Kotu: Joseph Egerton Shyngle, Ẹgba mọde Ọba ọkunrin

jẹjẹ abija kunkun: Eric Olawọlu Moore, ati Dokita abiyamọ nijọja: Curtis Crispin Adeniyi Jones ṣe oju ilu Eko yi—Njẹ ko ha han fun yin nisisiyi ṣe Ọlọrun lofi kiniun onibudo—ejo nigboro—para mọ lẹ, o kọ ọrọ wọ si, o kọ fun ara ile, okọ fun to de: Herbert Macaulay, C.E. (Iba ẹ o) ṣe baba fun ilu Eko yi?

Agba ẹnu ko ma le pa eṣinṣin o—Ẹma ye ẹnu mi—Shyngle doriṣa, Moore doriṣa, Jones doriṣa ẹni ofi dan ari dan; Macaulay, elore—Ẹkun aṣẹke—koyẹ kafi ọrọ yi ṣe itiju—Ẹṣe bi ọmọ oni nọ kunọ—ki ẹsin tọrọ idariji.

Ẹti lẹ duro nọ—kini ẹ nfi Ijọba pe! ẹ ṣebi wọn o mọ on ti wọn nṣe ni? Bi ẹ ko ba le ṣe iran lọwọ lati tun ilu ṣe—ẹ joko jẹ o.

ARALAMỌ.

---

## IMALE IBADAN BI ONIṢANGO ỌYỌ.

O jẹ ẹdun ọkan wa pupọ lati fi han awọn ọmọ Iya wa to jẹ Muslims, pe ko si Ilọwaju Isin ni Ebute Mẹta. Nkan to mu yi wa ni pe awọn agbalagba Ijọ ko fẹran ara wọn, olukuluku wọn lo nfẹ Ipo giga ni Ile Ọlọrun nwọn si nfẹ ki ọrọ-kọrọ ti wọn ba sọ iba jẹ ti ọmugọ tabi tọgbọn, ko jẹ bẹ, keta ati inunibini nja ijakadi larin wọn. Pupọ Igba ni aṣe akiyesi pe awọn alagba npẹ ki nwọn to ma wa si Jima; nitoripe nwọn mọ pe bi Imam ko ba ri wọn, nwọn ko gbọdọ kirun. Iwa yi yapa si ofin Ọlọrun pupọ. Ninu Mọshalashi 11 to wa ni Ebute Mẹta, o le ni 3,000 enia to wa nibẹ, ṣugbọn Irira, Keta ati Ẹgan ko jẹ ki a le yan ẹnikan ni Alufa Oniwasi, ki o ma ṣe wasi fun gbogbo Ijọ ni owurọ ọjọ Ọsẹ. Bi oṣu Awẹ ba ti le, gbogbo wa alakẹrẹgbẹ si Moshalashi, a ma fi idi ralẹ a ni a ngbọ wasi, nitori a ti mọ pe bi Awẹ ba pari, nkan a ṣe ẹnu re fun wa. Bi a ba ronu dada, gbogbo wa yio ri pe ọjọ 26 pere ni a fi nse wasi fun ara Ebute Mẹta lọdun kan. Ọkan wa ti di pẹta bi Irin *Railway* to wa ni Ile-edu Loko. Imale wa ṣe kilibọ. Laisi Igbọrọ Ọlọrun, ka si fi ṣe iwa hu, Irun-kiki wa jasi asan. Bi ko si ti oju awọn Amọdiya ti awa Imale Ebute Mẹta nwo ni, pupọ ninu ni ko ba bọ si inu aṣọ Egungun a ba ma Ilu Bata kiri Ilu. Iwa wa ni pe bi a ba ri awọn Amọdiya, a ma salọ kiak nwọn dabi kiniun fun gbogbo awa Ima gẹgẹ bi Anabi Mohammed ti jẹ Kiniun f awọn ara Ilu Mẹka. Iwa wa si jọ aw enia Noah, Nigbati Noah nṣe wasi fun w nwọn bẹrẹ si salọ, wọn sa pamọ, nwọn fi bori nwọn, fi ika ọwọ di eti wọn, nwọn fun awọn ọmọ ati aya wọn ki nwọn ma ọrọ Noah (Wo Suratu Nuah ninu Alk ẹsẹ 5 lọ de 8.) Irufẹ Iwa kanna ni a Imale nhu bi a ba ri Amọdiya, nwọn gbagbe pe Imale kanna ni wọn nitori ti nwọn nsọ sọ ọpọlọpọ Imale to ti ri s ibajẹ di were ọsan gangan. Ati kilọ awọn ọmọ ati aya wa ko ma gbọrọ Ọlọ ni ọdọ Amọdiya, ṣugbọn a ko kilọ wọn ki nwọn ma lọ mu Ọti *Dry G Whisky*, *Beer* ati Ẹmu-ayọ lori Tabili Ita gbangban nibi Oku tabi ibi Iyawo. yẹ ki awọn Imam wa wọnyi lọ ronu jinlẹ nwọn yan Alufa lati ṣe wasi fun wa lẹka lọsẹ, ki nwọn si fun awọn ọmọde laye la mọ ọna Ẹsin ni amọye si Ede Ilu wa lọ Amọdiya ki gbogbo wa le kuro nin Okunkun.

AJILARAN.

---

## ỌFẸ L' ẸLẸDẸ RIN D' ỌYỌ?

Bi iya nla ba gbe ni ṣanlẹ, kekeke a gori lofa ibere ti ọkan ninu awọn obinrin "Obilẹjẹ" bere lọwọ Bale rẹ pe, Ọga! mo gbọ pe nwọn gba orukọ nyin pẹlu t' awọn ti Ilu yan lọ si Igbi Aṣofin titun yi? "*Go way*" ki lo ṣe ọ to nb bẹ lọwọ mi? "*Nonsense*" Emi nikan ni nwọn gba orukọ rẹ nibẹ? Ha! Ọga!! a le f' eyi ṣe He! He!! He.!!! Anti Okete wa ba mi gbọ yi;—o-wi-bẹ kọ? Mi o mọ ore t' oriṣa ṣe Abuke to bimọ rẹ tan, to sọ ni Oriṣajinmi. B wa ko ṣiṣẹ ala silẹ, o ni, ọjọ ti mo mba ku, ki aṣọ ala bo mi.

Ẹjare Ẹ ba wa gbe orin yi lohun Mammy
Aluwanya.—Ẹni-mi-ṣe-ire-de !-A-rire !! 2.
Ẹni-mi-ṣika-o !! 2.
Ọlọrun-amu-dan-yin-dan-yin.!!!
Kiti-piri-Kiti-piri !
Alu-wa-nya.!!

OLOFINTOTO.

## IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS**—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£12—£12 10 fun *ton* kan.

EPO.

£24 10—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£19 10—£22 10 fun *ton* kan bakanna.

---

**KANO**—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—

Skins 1/10 per lb, Hides 4½d per lb

---


## *POSI T'O JIRE.*

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si :—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.

---

AIYELẸṢỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, Williams Street Lagos.

*Residence* :—135 Igbosere Road.

**Charges Moderate.**

**Cable Address :—**
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

**HAMBURG, Neurwall 16/18,**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

---

ẸGBE OYINBO ONISOWO

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16, 18, GERMANY.

Jẹ awọn ọnişowo ti ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ, ibaşe Ọja ti ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu Oyinbo miran ti o wa lagbeebe *England* ati *Germany*.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si ilu awọn Oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ ẹnia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn Oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) l'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Orukọ adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.


---

"EKO AKETE" GB'ỌRẸGẸJIGẸ.

A le ri Iwe-irohin yi ra lọdọ :—

(1) Ọgbẹni VIDAL R. COLE, Ajenifuja Store, 109 & 111, Broad Street, Eko.

(2) Ọgbẹni S. A. YEWANDE, 146, Griffith Street, Ebute Meta.

(3) Ọgbẹni MOSES O. JONES, Goi, Itẹsi, Abẹokuta.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

### ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30

7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

Masses ( Benediction ) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.

EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

### ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 6.30p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

### WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ereko | do. |
| 7 p.m. | do. | Rev. A. N. Cole |
| [illegible].30 a.m. | Olowogbowo | ,, E. F. Williams |
| [illegible].m. | | do. |
| [illegible].30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. C. W. Faulkner Shaw |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearce |

### AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | ,, G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | ,, A. M. Williams |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akiola |
| 6.30 p.m. | | Bro. Ade Olugbile |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. A. T. Fayan |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | |
| 4.30 p.m. | | |

### FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. R. O. Macaulay |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi ( Baptist ) | Bro. S. M. Phillips |
| 5 p.m. | | ,, John Apena |

### EBENEZER (BAPTIST)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | | Rev. A. A. Paddicombe |
| 6.30 p.m. | | Bro. J. Adekọya |

### BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. D. Adesanya |
| 7 p.m. | | Pastor. A. Adedeji Iṣọlá |

### St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. J. Adesanya

### AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọ[illegible] ( Bamgboṣe Street. )

### COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon ,

Rev. H. A. Lewis

### SALVATION ARMY.

10 a.m. Glover Memorial Hall, Capt A. Da Cos[illegible]

7 p.m. do. do. Major & Mrs. Grime[illegible]

### CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m Open Air Service T. W. Walleace & Wm. C. F. Terrell

---


### THE KANO PERISHABLE GOODS TRADERS, KANO.

About four months ago we seized the opportunity of railing certain perishable Goods ( Onions & Eggs) from Kano to Iddo local but during the 4th, 11th and 18th September ; we sustained a heavy loss on all the perishable articles railed to Iddo during the period, seeing these we made a petition through Mr. E. O Willit (D.T.S. Zaria) to Mr. Gibson, Acting Traffic Manager E.B. Having done this Mr. Willit promised us against further occurence and that such will not happen again, and that in future all perishable Goods ( Onions ) will be taken to Iddo direct. And in reality from that time such occurence has stopped, for which thanks we are much indebted to the General Manager, Traffic Manager and the District Traffic Supt Zaria ; and also the Senior Station Master Mr. Blaid who is rather social and expert in attending to people and the then Station Master, Mr. F. F. Henry, the Chief Goods Clerk Mr. F. B. Cole and the Goods Clerk self Mr. A. A. Dinna who is also social and expert in all undertakings. We beg the Railway to please make early arrangement for our perishable articles to avoid losses in future. We stop here today.

Cordially Yours,

( *Advt.* )

T. B. OSENI.

*The Secretary.*

21, Great Bridge Street, Lagos

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.


## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sã kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi ẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## IWE ITAN T'O KẸ RIRI

Ọrẹ,

Lọ ra Iwe Itan ti Ibadan ati ti Ọyọ ni Ile-itawe ti *C.M.S.* nibi, ṣile meji meji ati sisisisi ni a nta ọkọkan.

Ọgbẹni Isaac Akiyẹle l'o ṣe Iwe Itan ti Ibadan Ẹ o si ri ọwọ rẹ ninu ti Ọyọ pẹlu.

## BOOKS! BOOKS!! BOOKS!!!

"History of Ibadan" and "History of Ọyọ" by ISAAC AKIYẸLE are on Sale at the C.M.S. Bookshop, Lagos, 2/- 6d. each.

## JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared, Loans arranged Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

## MR. ỌLABOYE LALẸYẸ.

Licensed Auctioneer and Commision Agent undertakes to advertise largely and to sell satisfactorily any goods, house or landed property for sale by public Auction. He is also prepared on request to proceed any where in Nigeria for valuing and selling purposes and he makes it a point of duty to effect quick payment for goods or property sold.

For arrangements please apply at his "Iwa Rere" Mart, Faji Market, near Phillips' Medicine Store, Lagos, or his residence No 20, Fagbayimu Street Ebute Meta, selling days:—Monday, Wednesday and Friday from 9 o'clock a.m. till 5 p.m.

nranṣẹ KEJI,

Aṣọ Oke ... bẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ik fẹ lati lọ ba ...ita, ọpọku Ọyọku ni owo wọr ... 3 St. John Street, l'Eko, let...gbẹjọro.

## AWORAN ALARABARA.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile l'ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a lẹbi iku, ti onjẹ alẹ ikẹhin, t'owo lowo, a ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla ati ijọba rẹ ati nigbati o di ẹranko, ti obinrin ti o fi ọwọ mu ejo, ti Ọba Tatambulu.

Awọn Aworan wọnyi mbẹ bi aba, nwọn si pọ tase. Bi o ba fẹ ko pupọ, a le din ọ ni owo diẹ ki o ba le ri tirẹ jẹ. Iye owo wọn 3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan. 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila tabi *dozen*.

A ni Ewe-taba fun kika ta, Ọṣẹ-ọlọwọ agaga, Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ bi wọbu, bi o ba fẹ tọn a le ta a fun ọ, Iṣana alapoti fun tita ko si bi a ti nṣe wọn, orişirişi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma ri tirẹ jẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn, owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile Ọja wa, kami-kami ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa sibẹ.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe ṣọwọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBẸ & BROS.,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
( *Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis* )
Idumagbo.

---

## FOR SALE.

One Second Handed Triumph Motor Cycle in good working order.

Kick Start, 3½ H.P. with best magneto ( Bosch ) complete with front and rear lamps. Available for inspection.

*PRICE: MODERATE.*

Apply to the Editor.

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

— — —

AKI... CH!.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ aw... R. ... polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ...v. J. R. ...nu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri i... Bro. S. M. ...
.. John Ap...
(BAPTIST...
Rev. A. A. Pudo...
...ro. J. Adekọya

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless va... at 50, Dosunmu Street, Lagos.

**Prices to suit everybody.**

*Call now, fortune awaits you.*

---

## WO'BI.

Ile ọ̀wọ̀ ti awọn Ajọsẹ ti a npe ni S... Ireti nbẹ ti 24 Ita Agarawu nibiti a ... le ri orişirişi ṣ'ẹrẹkẹ ṣin ati ọti-amu-... ra, si tun ni Ẹka Ṣabu kan ni 10 ... Dosunmu nibiti ẹnikẹni le lọ ra ọja tire ... ọpọku ọyọku.

Ọrẹ, kọwe si :—

Ọgbẹni SOLO. S. AJOSE
*Alabojulo.*
ni 10, Dosunmu Street,
EKO.

---

## ẸNYIN ONIṢOWO EKO,

Ẹ wa polowo Ọja nyin sinu *Eko Akete* ... kolẹgbẹ ni ede Yoruba inu rẹ, o jare, o ... "ka-yin, wọbọ-wọbọ."

Ẹ tete sure wa, "Awure" nduro ... nyin !!! Owo pọ ọ ni yio na ọ, ẹnikeji.

---

## OGUN YANMUYANMU ATI EŞINŞIN.

( *Fly Catcher.*)

Eṣe ti o fi njẹ ki Yanmuyanmu ati Eşinşin ko arun ba ọ, nigbati ogun rẹ wa ni arọwọto rẹ. Ẹgbẹrun pere ni (3d.) Ẹdẹgbarun fun mejila ( 2/3d a dozen.)

A si ni ipari olorun amu irun dan daradara, o si ma njẹ ki irun sun mọlẹ, o njẹ ki o ma kọmọna bi jigin, ari malelọ awọ pada ẹhin. ( *Hair preparations.*)

Kọwe tabi bere l'ọdọ.

DIPO TUNDE & CO,
P.O. Box 335,
30, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

PRINTED AT "TIKA-... WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE I... ...LIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.